1261

# ALAYE LORI OFIN IṢẸ AGBẸ.

## ỌRỌ IṢAJU

Idi pataki ti a fi fẹ ṣe ofin yi ni lati fun Ijọba ni agbara ati mu eto ti a ti ṣe nipa iṣẹ agbẹ ni ilẹ Nigeria ṣẹ, pataki ẹyi ti iṣe ati jẹ ki awọn enia ki o ni itẹsiwaju ninu igbesi aiye nwọn, ki nwọn ki o si wa ni irọra.

2. Orişirişi ọna ni a le gba ran awọn agbẹ lọwọ lati ri ere pupọ fun lãlã wọn ati lati le ri ọpọlọpọ onjẹ, ti o dara ju eyiti nwọn nri nisisiyi lọ fun ara wọn ati idile wọn. Ohun ti ofin yi wa fun ni lati jẹki awọn nkan oko (produce) ti a nfi ranṣẹ si ilẹ ibomiran dara lọpọlọpọ, tobẽ ti nwọn yio fi le ta dada ni ọja agbaiye, ati lati mã pa wọn mọ kuro ninu orişirişi árun gbogbo ti o le bà wọn jẹ.

3. Gbogbo wa ni a mọ pe ohun iṣoro pupọ ni fun ilu ti o ba npọ si tabi ti o ba ntẹsiwaju, yala ninu ilera tabi ọrọ, lati le ri onjẹ ti yio to fun gbogbo awọn enia wọn mu jade lati inu ilẹ wọn. Nitorina fun ire awọn enia Nigeria, a ni lati wa ọna ti arun ohun-ọgbin tabi kokoro buburu ko fi ni wọ ilu wa eyiti o le mu iparun nla wa sori awọn nkan oko wa bi iṣu, agbado, ọka baba, gbaguda tabi irẹsi. Ọpọlọpọ awọn ohun-ọgbin ti a njẹ bawọnyi ni o ti bajẹ tabi to ti run ni awọn ilu miran ti igbà ko ba dara tabi ti awọn kokoro buburu wọnyi ba kọlu wọn. Ọrọ iyàn ko jina si awọn ilẹ ti o mẹta. Nitorina, ohun pataki ni fun Ijọba lati lo ọna ti a nlo ni awọn ilu miran ki iru ofo bayi ba le jina si ilẹ Nigeria.

4. Ki awọn ohun ti a nfi ranṣẹ si ilẹ miran ba le ma dara, Ijọba gba iwọn bi ẹdẹgbẹta aşãsan, pẹlu awọn akọwe ati alabojuto si iṣẹ. Iṣẹ yi ko na awọn enia Nigeria lowo pupọ, nitoripe diẹ ninu owo ti a nsan fun awọn oşişẹ wọnyi ni a nmu ninu owo ori, owo ti a ba gba fun ibẹwo ni a fi nsan iyoku. Ohun pataki ti awọn onibara wa loke okun ntẹnumọ ni pe bi a ba fẹ gba owo ti yio tẹ wa lọrun fun awọn nkan oko (produce) wa, a ni lati wa ọna ti awọn ohun-ọgbin na yio fi ma dara lọpọlọpọ.

5. A ni ireti pe awọn enia Nigeria yio ṣe ojaşe wọn nipa şişe ofin nitori awọn orişirişi arun ati kokoro ti o le ba awọn nkan oko jẹ ati lati jẹ ki awọn nkan oko na dara. Nitorina, ofin ti a fẹ ṣe yi pese fun idasilẹ Igbimọ kan, ninu eyiti enia dudu pọju, lati ṣe eto fun itọju awọn ohun-ọgbin wa li ọna ti awọn enia fẹ.